# AWỌN IYỌNU MEJE IKẸYIN
## Ifihan 15:1-8; 16:1-21
## ẸKỌ 463 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Bẹ̄ni, Oluwa Ọlọrun Olodumare, otitọ ati ododo ni idajọ rẹ" (Ifihan 16:7).**

**Orin Iyin**

Lati ibẹrẹ titi de opin Iwe Ifihan ni a n fi iyin awọn ẹni irapada wé ipohunrere ẹkún ati ifibu (egun) awọn wọnni ti wọn korira Ọlọrun, ti wọn si kọ̀ lati gbọran si I. Johannu kọwe pe nigba ti a pe oun lati wa wo Ọrun, oun ri Itẹ́ kan lori eyi ti Onidajọ gbogbo ayé joko. Niwaju Itẹ́ naa ni okun digi, ti o mọ́ bi kristali wà (Ifihan 4:6). O ri Iwe kan ti a fi èdidi meje dí, eyi ti Ọdọ-Agutan nikan ni ẹtọ ati ṣí. Johannu ri awọn idajọ ti o ba ni lẹru ti a tú dà sori ayé bi a ti ṣí awọn èdidi meje wọnyii ni ọkọọkan. Johannu gbọ́ iro awọn fere meje bi a ti tun n dà idajọ ti o tobi ju ti iṣaaju lọ sori ayé. Sibẹ laaarin idajọ wọnyii, lati igba de igba ni Johannu ri ogunlọgọ awọn ẹni irapada ti o wà lai lewu ni Ọrun, wọn si n kọrin iyin.

Ninu ori kẹẹdogun, a kà nipa iran Johannu nipa ogunlọgọ awọn eniyan ti a rà pada lori okun digi eyi ti o dapọ mọ́ iná ni akoko yii. Awọn ni a kà nipa rẹ̀ ninu ẹkọ wa ti a ṣe kẹyin -- awọn ti o la idanwo iná nla kọja ti wọn si ti kú ikú ajẹriku nitori wọn kọ̀ lati gba ami ẹranko nì. Nihin, Johannu ri wọn ni Ọrun, wọn duro lori okun digi, wọn n kọrin, wọn si n lu harpu.

**Mose ati Ọdọ-Agutan Naa**

Orin wo ni wọn n kọ? Orin Mose iranṣẹ Ọlọrun, ati orin Ọdọ-Agutan. Nibo ni o rò pe wọn ti kọ́ orin Mose? Lai si aniani ninu Iwe Ẹksodu ni, nibi ti a ti kọ akọsilẹ orin iyin Mose si Ọlọrun nipa mimú ti O mú ogunlọgọ awọn Ju kọja ninu Okun Pupa ti O si fun wọn ni iṣẹgun lori awọn ọta wọn.

Nigba wo ni wọn si ti kọ́ orin Ọdọ-Agutan? Boya nigba ti a ti rà wọn pada nipa irapada nla ti Jesu, Ọdọ-Agutan Ọlọrun ti fi Ẹjẹ Rẹ̀ iyebiye rà fun wọn. A ti fun wọn ni iṣẹgun lori ẹranko naa eyi ti eṣu ti gbé dide gẹgẹ bi adánikan-paṣẹ lori ilẹ ayé, Johannu ri wọn bi wọn ti n lu duru Ọlọrun ti o lẹwa pupọ, wọn si n kọrin pe, "Titobi ati iyanu ni awọn iṣẹ rẹ, Oluwa Ọlọrun Olodumare; ododo ati otitọ li ọ̀na rẹ, iwọ Ọba awọn orilẹ-ede."

**Ibinu Ọlọrun**

Lẹsẹkẹsẹ ni a ṣí ilẹkun Tẹmpili ni Ọrun -- Tẹmpili ti Ọlọrun ti fi han Mose nigba ti wọn pade ni Oke Sinai. Ọlọrun ti sọ fun Mose lati kọ́ ọ̀kan bi iru rẹ̀ fun awọn Ọmọ Israẹli. Nigba ti a ṣi ilẹkun naa, lati inu Tẹmpili yii ni awọn angẹli meje ti jade wá, a si wọ̀ wọn ni aṣọ ọgbọ funfun ti o mọ́ lau, a si fi amure wura dì wọn lẹgbẹ. A fi ago tabi igo ti o kún fun ibinu tabi irunu Ọlọrun fun ẹni kọọkan ninu awọn angẹli mejeeje wọnyii.

A kà ninu Bibeli pe, "Ọlọrun si nbinu si enia buburu lojojumọ" (Orin Dafidi 7:11), ati ni igba gbogbo lati iṣẹdalẹ ayé wá ogunlọgọ awọn eniyan ni wọn n bí Ọlọrun ninu nipa iwa buburu wọn, agidi wọn ati iwa ọ̀tẹ wọn. Nisisiyii, a o da ibinu Ọlọrun le ori awọn wọnni ti wọn kọ̀ jalẹ lati ronupiwada ati lati kaanu fun ẹ̀ṣẹ wọn.

Awọn eniyan inu ayé ko mọ pe awọn angẹli wọnyii ti mura tán lati tú igo ibinu Ọlọrun sori wọn. Wọn n ba iṣẹ wọn lọ gẹgẹ bi wọn ti n ṣe tẹlẹ ri. Ṣugbọn ki ni ami nì ti o wà ni atẹlẹwọ wọn tabi ni iwaju wọn? Eyi ni ami ti wọn gbà ki wọn ba le rà tabi ki wọn ba le tà nigba ti wọn ba lọ si ọja ounjẹ, tabi si ile itaja ohun ọṣọ tabi si ọdọ awọn ti n ta ọkọ ayọkẹlẹ. Awọn oniṣowo ko le ta nnkan kan fun ẹnikẹni ti ko ba ni ami ti o fi hàn pe o tẹriba fun iṣakoso ati aṣẹ ẹranko naa. Wọn pinnu pe o ṣe anfaani lati ra ounjẹ, ohun ọṣọ, ile ati ọkọ ayọkẹlẹ ju lati jẹ́ olootọ si Ọlọrun Ọrun lọ.

**A Tú Ibinu Jade**

Lojiji, awọn ti wọn ni ami ẹranko naa ri egbo kikẹ nlá nlà lara wọn. Angẹli kin-in-ni ti tú igo rẹ̀ si ori ayé. Nigba naa ni awọn atukọ inu ọkọ oju omi ji ni owurọ ọjọ kan, ti wọn si ri i pe òkun ti di ẹ̀jẹ. Gbogbo ẹranko omi, gbogbo ẹja ati gbogbo erinmi kú nitori kò si omi. Angẹli keji ti da igo rẹ̀ sori òkun. Awọn eniyan inu ilu nla ati ilu kekeke ri pe ẹjẹ ni o n jade lati inu ẹrọ omi wọn nitori angẹli kẹta ti tú igo ti rẹ̀ sori orisun ati odo gbogbo, omi si ti di ẹjẹ. Johannu gbọ́ angẹli miiran bi o ti sọ fun Oluwa pe o dara gidigidi ati pe o si tọna ti nnkan buburu yii ṣẹlẹ, nitori awọn eniyan buburu ti pa, wọn si ti ta ẹjẹ awọn eniyan mimọ́ Ọlọrun silẹ, eyi si ni ère ti o tọ́ ti o si yẹ fun wọn.

Nigba naa ni oorun ràn pẹlu ooru ti n jo ni, awọn eniyan si di alara rírọ nipa rẹ̀. Ṣugbọn dipo ki wọn ronupiwada ki wọn si bẹbẹ fun aanu lọdọ Ọlọrun, wọn ṣọ̀tẹ si Ọlọrun, wọn si sọ ọrọ odi si orukọ Rẹ̀. Nigba ti wọn si n joro egbò, aini omi, ati ooru ti n jo ni, okunkun biribiri bo olu-ilu ibi ti ẹranko yii ti n ṣe akoso, awọn eniyan si n gé ahọn ara wọn jẹ nitori irora. Sibẹ wọn kò ronupiwada ṣugbọn wọn sọrọ odi si Ọlọrun.

Awọn angẹli wọnni n tú awọn ibinu wọn si ori ayé sibẹ, odo nla ti a n pè ni Euferate si gbẹ. Awọn ẹmi eṣu ni iri awọn ọpọlọ jade lati ẹnu dragoni naa wá ti n ṣe eṣu ati lati ẹnu ẹranko naa, ati lati ẹnu wolii eke naa. Awọn ẹmi buburu wọnyii ṣe awọn iṣẹ ami nla wọn si rọ awọn ọba ayé lati pade ni ibi kan ni Palẹstini ti a n pè ni afonifoji Megiddo (2 Kronika 35:22). Awọn ọba ila-oorun ko mọ ohun ti o ti ṣẹlẹ ni Ọrun, ṣugbọn a mu ki ọna rọrun fun wọn lati lọ si Palẹstini. Wọn ko mọ pe Jesu yoo wá sibẹ pẹlu ẹgbaarun awọn eniyan mimọ́ Rẹ̀. Bẹẹ ni wọn ko si mọ pe lakoko yii gan an ni a o tú ibinu keje ti o kù ninu idajọ ikẹyin lati ọwọ Ọlọrun jade. Johannu gbọ́ Ohùn nla kan lati inu Tẹmpili wá, ati lati Ori Itẹ́ ni Ọrun, wi pe, “O pari.”

A si gbọ́ ohùn pupọ, ààrá, ati manamana, yinyin nla -- ọkọọkan ninu awọn yinyin nla wọnyii ju ọgọrun ẹ̀sún lọ -- ati isẹlẹ nla ti kò si iru rẹ̀ rí. Njẹ o ti ni iriri isẹlẹ rí? O le sare lọ sori igi tabi opo ogiri ọgba lati duro daadaa, ṣugbọn eyi paapaa n mì pẹlu. A, bawo ni eniyan yoo ti jẹ́ alailera to nigba ti Ọlọrun ba mi ayé!

Ẹranko naa, awọn ọmọ-ẹyin rẹ̀, awọn ọba ayé, ati gbogbo ogun buburu ayé ṣubu labẹ agbara Ọba awọn ọba. Oluwa wa Jesu Kristi, Ọdọ-Agutan Ọlọrun. O fi eemi ẹnu Rẹ̀ pa wọn, O si fi didán wiwa Rẹ̀ pa wọn run (2 Tẹssalonika 2:8). Awọn idajọ naa pari.

**Gẹgẹ bi Ole**

“Kiyesi i mo mbọ̀ bi olè. Ibukún ni fun ẹniti nṣọna, ti o si npa aṣọ rẹ̀ mọ́”. Jesu n bọ̀ kánkán, lai rò tẹlẹ, gẹgẹ bi olè. Fun awọn ti wọn fẹran Rẹ̀, ti wọn si pa aṣọ igbala wọn mọ́, yoo jẹ́ ọjọ ayọ̀; ṣugbọn fun awọn ti wọn kọ̀, ti wọn si ṣọtẹ, yoo jẹ́ ọjọ ti o ba ni lẹru, ọjọ ibanujẹ wahala ati ikaanu. Ọjọ wo ni yoo jẹ́ fun ọ, ọjọ ẹru ni, tabi ọjọ ayọ̀ nla?

**AWỌN IBEERE**

1. Iru awọn eniyan wo ni o wà ni Ọrun ti o duro lori okun digi, ti awọn ti harpu Ọlọrun?
3 Orin wo ni wọn n kọ?
4 Ta ni jade lati ẹnu ilẹkun Tẹmpili ti a ṣí ni Ọrun?
5 Iru aṣọ wo ni wọn wọ̀?
6 Ki ni Ohùn nla lati inu Tẹmpili naa sọ fun awọn angẹli meje wọnni?
7 Njẹ awọn eniyan inu ayé n reti awọn idajọ nla wọnni ti a dà sori wọn?
8 Njẹ wọn kaanu fun ẹ̀ṣẹ wọn, bi iyọnu wọnni ti n wá sori wọn ni ọkọọkan?
9 Ki ni mú ki awọn ọba ayé wá si Palẹstini?
10 Ki ni iyọnu nla ti o kẹyin? Ki ni ohun ti awọn eniyan si ṣe nipa rẹ̀?
11 Bawo ni wiwá Jesu yoo ti ri?